LADIES AND GENTLEMEN. If you want to look smart when you go to the Glover Hall YOU MUST pay a visit to

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. IV. No. 157. SATURDAY, JULY 18, 1925. 4d.

**Declared Circulation 1,700 Copies Weekly.**

## White's Golden Female Tonic
**(NATIVE)**

A splendid Remedy for female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

**Price 10s. per Bottle.**

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*Packing & Postage 2/6d. extra.*

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
OYINBO **J. F. SICK**
Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Ölokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Iş'ọşọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

JOHN HOLT'S NEW BROAD STREET SHOP.

Everything for the Dance and at the lowest possible prices in Lagos.

# LEVER STORE

EBUTE METTA.

# GREAT SUCCESS

## WONDERFUL VALUES

SPECIAL

# Large Assortment

OF THE

# FINEST MEDICINES.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices :* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/ |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/ |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—— .o. ——

ALUFA ALAKIKANJU, O DI SA KAN O.

Alufa S. C. Phillips, Alabojuto Ijọ C.M.S ni Ode Ondo dakan wa sibi fun Ipade Ijọ Igbimọ C.M.S nilẹyi ati fun Iyawo aburo rẹ, Ọgbẹni T. K. E. Phillips, Aforin-jiṣẹ-Oluwa, o si pada lọ sẹnu iṣẹ ni *Tuesday* ọsẹ yi. Ọna re o!

KINLA ?

Otitọ ha ni ọrọ ti a gbọ lati Ibadan wa pe, a ti rọ Shittu loye Balẹ Ibadan, ati pe ẹlomiran lo tun rọpo rẹ nisisiyi?

ẸNYIN AGBA IṢẸRI, Ẹ KU ETUTU.

Ninu ọsẹ yi la ri awọn Oloye Agbagba kan pẹlu awọn Isọgbe wọn ti nwọn sọpe nwọn de silẹ yi lati Iṣẹri lati feti Ijọba kan ẹniti nwọn npete lati fi sipo Ologbe Odunsi Sarumi Ọlọfin Iṣẹri ; a si gbọ pe nwọn ti lọ ri Aṣoju lẹmeji nipa ọrọ na, ati pe nwọn si ti kọwe ohun ti nwọn ba wa si i. Ori Ọlọfin a gbe nyin.

A o tun sọ si ọrọ yi laipẹ.

ABỌ O. ỌMỌ LAKESI.

A ki Mrs. D. Ayọdele Bright kabọ lilọ to lọ si Abẹokuta ni ọjọ Alaruba ọjọ kẹjọ oṣu *July*, 1925, to de ni Satide ọjọ kọkanla to lọ wo aburo rẹ Miss Ọmọwale Ọbadina to ṣe ni'lọra, ki Oluwa Ọbangiji ko gbe dide laipẹ, ko si fun u ni ara lile.

AKURU YẸ'JO, Ẹ KU AṢEHINDE.

A ba Ọgbẹni I. B. Byass (Akuru) ti *Bishop Street*, Ọga kan ni *Nigerian Railway*, kẹdun afẹku iya rẹ, ẹniti o terigbaṣọ lọṣẹ yi.

Bẹ si ni a tun ba Ọgbẹni na yọ fun "ẹhin ọta" rẹ to ri na ; ijinlẹ Yoruba leyi. A pe Ologbe na ni "ọta" ọmọ rẹ ki iṣe ọta iyọta gẹgẹbi a ti mọ itumọ ede na si, "ọta" ti a pe Ologbe na ni pe, a ba Ọgbẹni Akuru yọ nitoriti ko ku ṣan iya rẹ loju ; ka jẹ pe o lọ ku ṣān loju nkọ? Tani obi ti o ngbadura iyẹn? A ko ha ri gbajumọ ọkọnrin miran ti on ati iya rẹ wa lāye, ṣugbọn ti gbajumọ na ja fau to si fo ṣanlẹ ku mọ iya rẹ loju, bi ede "ọta" ti a lo ti gbe rebẹ.

---

CHRISTENING.

"Elsie Rosaline" were the two Christian names given to the child of Mr. and Mrs. S. A. Temple Cole of 51, Oke Suna Street, whose christening was consummated at Christ Church Pro-Cathedral at 10.30 on Sunday the 12th instant.

Before the Vicar was out from the Vestry a number of Ladies and Gentlemen was seen anxiously awaiting that eventful minute when the innocent babe would be received into the fold of Christ with the usual ceremony.

The Vicar being ready the short ceremony for women's churching was gone through at the altar after which all gathered round the font when the Rev. Vicar in his usual graphic tone sonorously read the Baptismal Ceremony

Prominent among the guests were the following :—

Mr. Rhodes, Barrister-at-Law, Mrs. Abimbola Gibson, Mr. and Mrs. M. A. Obafemi, Mr. King of the Sanitary, Mr. Mends-Cole, Miss Macaulay, daughter of Mr. Herbert Macaulay, C.E., Mr. Okorodudu, Mr. and Mrs. Emeric Johnson ,Mr. Shackleford and several others too numerous to mention.

The ceremony being over the guests repaired to the Host's and Hostess' where sumptuous repast and drinkables were served profusely to the satisfaction of all.

Mr. Mends-Cole enlived the Company with his humorous wits and made some people to laugh until they cried.

The sweet gathering dispersed after splendid toasts and speeches with Mr. Mends-Cole as the Chairman who ended with a very Solemn warning undoubtedly impressed the minds of everyone there present. Everything being over the Table closed with a benediction.

We wish both parents and babe a long lease of happy life.

[ *Communicated.* ]

# IȘELU.

## "AGBA O SI ILU BAJẸ, BALE ILE KU ILE D'AHORO."

Si Oniwe-Irohin "Eko Akete."

Iba o!

L'ọsẹ to kọja a sọ diẹ ninu iṣẹ iwe irohin, a kan yan a ṣa-ṣa-ṣa ni nitori aye ko le si lati sọ to bo ti yẹ. Pataki ti ko ni tabi-tabi ninu li a si sọ, iwọnyi ni pe oniwe-irohin ni lati fi iwe rẹ wa ire ati anfani ilu nipa otitọ ni sisọ, itọsọna fun ilu ati Ijọba, ẹtọ nidi ọrọ, lai duro ti ọtẹ, lai ṣe abosi, lai ṣẹtan. A si ke si ẹnyin ilu papa lati ma wa otitọ, k'ẹ si ma duro ti i. Ebu ati ọrọ wọnrọn-wọnrọn ki wu ilu atata lori ki si nkun wọn loju. Ọrọ iṣiri, ọrọ ebu, ọrọ ọgbọn, ọrọ lakaye, l'ọrọ kan, ọrọ ọmọluwabi to yẹ enia on na ni eyi to yẹ iwe-irohin, nitoripe gbohungbohun ati awo-jiji ni iwe-irohin jẹ. O nkọ ilu ni ọlaju atata ati ọgbọn ilọsiwaju, o si nkọ ilu ni ọrọ ati iwa eri, ede ara-o'ko ati ilasẹhin. Oriṣi mẹta ni iwe-irohin Eko pin si nisisiyi. Awọn kan wa gẹgẹ-bi alatako awọn alakoso-ilu ni ti wa: awọn na ni nwọn dabi agbe f'Ọba. Awọn iwe wọnyi lo duro gbangba pe ti Ibikunle wọ fun awọn, ki Ijọba ṣe kokari rẹ lalai bẹru, lalai mikan. Nwọn mọ pe aṣa-ilẹ wa ni pe Ọba ti ilu ko ba kọ, Ọba ṣini. Ṣugbọn nitori ailẹṣẹnilẹ wa nwọn diju si eso ti igi-oro ti nwọn fẹ lọ yio so l'ọla.

Awọn iwe miran si wa, ẹwẹ, ti nwọn duro wanle pe aidara ati aṣiṣe Ijọba ṣa ni nwọn ba l'ọrọ. Nwọn nṣe hatihati l'ọna arekereke ti ilu ko le fi ri ọwọ wọn. Awọn wọnyi ni nwọn nkigbe to, ni nwọn ṣe fiṣan pe ewọ, "Ọba ko ku, Ọba ko jẹ" bẹ nwọn ko fi iwe ṣe ẹtọ fun ilu pe, egbe re, egbe re; nwọn ko fẹ gbọ sisun, nwọn ko fẹ gbọ wiwi, alalikua nwọn ko le ta putu ti igbẹ ba fọ, Ki nwọn si ronu lasiko? Agbẹdọ o, Ti nwọn kọ, Eni ba ṣa nsunkun asundabọ li a npe o kẹdun ẹni. Ọgbọn janduku ti nwọn fi nfọ gbogbo rẹ l'oju pọ wẹ, ju eyi ti ọgbẹri le ṣakiyesi lọ. Awọn iwe bawọnyi ṣe ibi ju ti agbe-fọba lọ, nitori ẹni nfi aidara siwaju Ijọba ṣe tirẹ s'ọna kan fun ẹnikẹni lati yẹwo. Ṣugbọn ẹni ti nja ija awuruju, iyẹn ko ṣe da lẹjọ, nitori ko ni jẹ o wi.

Awọn iṣi-kẹta iwe-irohin wa ni awọn ti nwọn duro gende fun rawọn lati ṣe iranlọwọ fun ilu wa. Nwọn ni awọn ko ṣọtẹ awọn ko si ṣ'eru. Ti wọn ni pe ki kaluku mu ọna ire pon k'o si fi inu kan gbọ ti ilu. Awọn wọnyi wa jẹ asoṣọkọ ti ẹnu wọn ki ran lẹ L'ọtun, nwọn ngbun awọn ajirọba, l'osi nwọn nb'awo jẹ fun awọn atolugbokun-agbọnakan-kan.

Bi ti Eko si ti wa buaya to, a ko ri agba mọ ni ilu. A tọrọ gafara. Agba ko si, nwọn iba wa gbogbo rẹ ko le lọju-lu bayi. Ko ba jẹ pe bi awọn aṣiwaju awọn oṣelu wa ode isisiyi ti nṣe ni awọn nṣe ni ko ba ti pọ to bayi. Ṣe on ni nwọn ṣe nkọrin pe:—

"Bayi la ṣelu ilu iba dun—
Bayi l'a ṣelu!"

Eko ni asiki. Eko ni ori-ire. Ṣugbọn Eko ko ni enia to le ṣe bi agba. Ti awọn kuruntu ilu ko l'a wi. Awọn oniwe tabi Kiriyo to laju, to finju, l'a nwi. Bi ko ba si ti aito-enia a le sọ pe irufẹ Eko yi pẹlu awọn Giriki ni iwe, ni owo, ti nwọn, wa ninu rẹ nwọn ko le ṣatilẹhin fun Ilu ki orukọ ilu ma ga si, ki alubarika ati asiki ilu si ma pọ si?

Saro ko gbe Eko ni iye enia to mọ iwe jina; Saro ko ri ibi ko l'ẹgbẹ Eko l'ọna ti alumọni; bẹni Saro dẹ san ju wa lọ. Awọn alagba Saro pe ara wọn l'enia ni njẹ bẹ.

Ẹla l'ọrọ, a o ṣe akawe meji mẹta.

Ipalẹmọ ti Arẹmọ Ọba Oyinbo ko ṣai ni yanyan ninu ni Saro ati ni Ilu Agọnyin gẹgẹ bi o ti ni larin wa nibi. Ni Ilu Saro, Ọgbẹni Ṣorunkẹ Sawyerr *Lawyer*, ni ẹni ti o kọkọ sọlu eto ti Ijọba wọn lọhun ṣe. *Lawyer* Bankọle Bright si ni ẹni to sare ta a laiya. Bi o ti jẹ pe iyi ati ẹyẹ Ilu wọn ni gbogbo wọn nja fun to, Lọya Bright ti a wi yi ni ẹni to gbe ipinnu kalẹ fun Igbimọ-Iṣelu (*Legislative Council*) pe Iwe-Ikini ti Balẹ pẹlu awọn ara ilu nikan ti to, ki Igbimọ ma ni omiran mọ bi ko ṣe bẹ yio dabi ẹnipe nitori iyẹn jẹ Dudu ni Ijọba ṣe tun fẹ ti Igbimọ. On pelu awọn Ẹgbẹ rẹ l'o pinnu lati gbaruku ti ipinnu yi.

Ọrọ koi de bẹ ti Gomina wọn (Slater) ti nanu mu Bright to bu u yanna-yanna pe Ọlọtẹ enia ni. Ati Balẹ to ni ipo ni Igbimọ-ilu, ati awọn yoku lo wọ ṣin nigbati nwọn ri ina ti o jade loju Gomina. Sibẹ iwe-irohin gbogbo lo kinrin Bright lẹhin. Sibẹ na, Ijọba ṣe ti inu rẹ ṣugbọn, gbogbo awọn Oṣelu lo fẹnu ṣọkan ba Ijọba jiroro ti nkan miran ti Ilu fẹ fi jẹ ṣiṣe ti gbogbo rẹ fi yẹ wọn de gere.

Ni Ilu Agọnyin, ẹwẹ, ati Ofori Atà ati Oforiatá ni nwọn so-wọ pọ ṣe ti wọn, to bẹ ti Ẹyẹ na fi pọ rekoja. Ofori Ata lo ka Iwe-Ikini ti Igbimọ; Brown lo ṣa a jọ (*draft*); Ẹgbẹ *Aborigines* (Ibi-lẹ) ṣe iwe ti wọn, Ẹgbẹ *Congress* ṣe ti wọn, awọn Obirin tabi Iyalode lo na awọn iwe wọnyi si Ọmọ Ọba ninu Ipade pataki ti wọn; awọn Ọba ti apakan fi Iwe tiwọn fun u. Gbogbo Ọba pọ si tun fun u bẹ. Apoti Wura si ni kaluku fi Iwe-Ẹyẹ tirẹ si fun itan-ọla. Awọn Adajọ ati Lọya si gba Arẹmọ Ọba ni Kotu wọn ki o foju ri Ile Ododo Gẹsi.

Awọn ọmọde Ilu ma ti ko ebu ti Casely Hayford (Makọli Ilu Agọnyin) ati Van Hien wipe nwọn jọdi ni lati ba awọn Brown ati Ofori Atà ṣe iwe pọ. Ko gbodọ bajẹ nikan, l'esi ti Ọlọla Hayford fi. Ẹ ko ri nkan?

Tani le sọ pe awọn wọnyi nwọn ki nṣe Agba? Eyi fihan ẹnyin ara Eko pe ija ti "Ẹni ti ko ki ni ku-ile padanu ku-abọ," "Egun kọja o ni on ko ri Gọntọ. Gọntọ ni on papa ko tilẹ mọ pe akisa kan ha si para" ni ti awọn Oṣelu Eko. Nibo ni mo wa ni tiwa. "Ẹni ti ko fi t'emi ṣe, ọbọlẹ ki i" ko si ninu a nwa iṛe ilu. Oṣelu ma nni suru nwọn si ma nfi lakaye gbe e. Ni ọ lun kẹrinla lọhun, ni Ilu Oyinbo, awọn *Liberals* fẹ lati ge iyẹ awọn Ọlọla (*Lords*) nitori jamba ti nwọn ma nta ọpọlọpọ ofin itunilara. Ọrọ yi di firigbọn awọn, Koyẹ (*Conservatives*) taku. Ṣugbọn nigbati Asquith (to wa di Oloye *Earl Oxford* nisẹnyi) fi ake kọri pe bi Igbimọ ba sọ, on yio gba aṣẹ lọwọ Ọba King lati da enia lola to lati le mu ofin na jalẹ. Balfour pẹlu Lansdowne sorikodo nwọn si gbojẹgẹ. Ologbe Halsbury fọpa tisẹ jade lati ṣiwaju awọn Wonkoko (*Die-Hards*) ṣugbọn awon Balfour ati Oloye Lansdowne mọ pe ti oporo Oloye ba wọ Ile Oke (*House of Lords*) yio di ṣiṣe ko si ni mọ bẹ mọ, nitori awọn ṣẹkun wọnyẹn yio gba agbara *Tory Lords*, awọn Ọlọla ti Ẹgbẹ tiri, ti nwọn ti pọri ju ti Egbẹ Asquith lọ. Lakaye ti nwọn fi ṣe ko jẹ ki Asquith lọ siwaju mọ, nitori o ti ṣe kilọkilọ nwọn si ti ri pe bi awọn ko ba yara faye silẹ igbẹhin yio buru fun wọn. Maja-masa bẹ ni gbogbo Oṣelu nṣe ki nkan ma ba bajẹ. Aṣiwaju ki jẹ ki nkan bajẹ mọ on lọwọ. Eko iwoyi nikan ni boti-leri-kori ngba po lọwọ ẹrọ, ati lakaye. Bi a ba nbu awọn ọta ilu ki a ranti pẹlu pe awọn ti a fi ṣe atọkun papa ni lọwọ nwọn si di kun agbọn. Ijafara wọn pọ ju ti Ilu lọ. Iyẹn lo mu iwe alarabara, oni tẹn tẹ-kutẹ, wa. Iyẹn lo mu ebu ainidi wa. Ọna ẹtọ ni lati yan awọn Agba lọ ba Balẹ-ilu lati ṣe abere-ẹhin ti ebu awọn Oloye. Bakanna si ni a ba ti fi ẹrọ mu ọrọ Ọba wa, ti a ba si dide duro gbangba ka fi ẹṣẹ si. Iba yin o.

KEKERE ILU.


## Cheap, Neat and Artistic Printing.

Send all your matters for printing to

THE EXCELSIOR PRESS

EBUTE METTA, NIGERIA.

*Offices* :—144, Denton Street, Ebute Metta

*Works* :—1, Glover Street, Ebute Metta

*Managing Proprietor* :—

B. ADE: MUMUNEY.

We specialise in Card Printing of all descriptions, Programme, Leaflet, etc., etc.

**Try us and see !!!**


## THINGS WE WANT TO KNOW.

1. Where did the Ecclesiastical Court orignate? Who was the first offender, and what was the offence, and also the verdict or result of its findings.

2. Can you advise me how Ladies can be well dressed, without being expensive, in attending Weddings and Ball Room Parties, and any other social gatherings?

3. Sometime ago it was, I believe, the "craze" in town to follow certain trade or profession to the extreme *viz*: Law, Auctioneering, Barbing, and now our womenfolk are observed to give you a sort of "cookery diet" and of late "a well roasted corn" to keep you chewing in an agreeable company! Can you explain?

4. Why are the Police pointsmen, still unprotected during the heat of the sun and cruel blast of the rain. Cannot the Inspector General suggest a remedy, please?

5. What is the cause of the recent riot in the Prisons—anything wrong with the Chief Warder? Or any responsible to keep order and discipline?—Director Stone may be able to say.

6. Is it not necessary for all single women to work before they get married or acquire husbands, if so, where can they all be supplied with work?

7. Many a man suffers from writer's cramp owing to the nature of their work, and it is very much afraid too-many a Preacher, and Public Orator suffers from thinking paralysis?

8. Is not the motor traffic a danger to pedestrians, owing to the width of the streets especially congested area?

9. What is the best advice to give young married couples re keeping of friends, and ringing off busybodies?

10. Are not Christians, Muhammadans, and Pagans agreed that there is a Divine Being, if so, why worry about creeds and dogmas?

11. Say what you mean, and mean what you say, seems a golden precept to talkatives, talebearers, etc.

12. Do the Pulpit know that there are more mortgaged properties in Lagos, than they can imagine, if so, are they less interested in the temporal welfare of their members, than their religious side, why not pray for the prosperity of Lagos and so be in sympathy with the Pew?

MARY BULL.

## IROHIN MINNA.

[ Lati owọ PROFESSOR BUBUYEH. ]

### INA TO JO'LE ỌMỌ IJẸSHA, ẸWA LO BUSI.

Inu gbogogbo ọmọ Ijẹṣa Minna dun pupọ nigbati wọn ri arakọnrin wọn Ọgbẹni I. S. Ọgini Johnson afinju ọmọ Ijẹṣa ti o pari ile rẹ ti o kọ ni panu eyiti o ti fi koriko bo ri ti ina si jo patapata ati ohun gbogbo ti o wa ninu ile na, ṣugbọn iranlọwọ si wa fun arakunrin wa yi lati ọdọ Ọlọrun wa, o si tun ile na kọ, o si bo ni panu, ẹwa rẹ si tun pọ ju ti iṣiwaju lọ. Njẹ ina to jo'le ọmọ Ijẹṣa ẹwa lo busi. Ki Ọwa ko pẹ.

### ẸGBẸ EKITIPARAPỌ.

A gbọ pe awọn ọmọ Ijẹṣa fẹ da Ẹgbẹ yi silẹ ni Minna, gẹgẹ bi wọn ti da ọkan silẹ ni Zaria eyiti a gbọ pe Thomas ara Oke Ijọka (ọkọnrin kọkọbọtọ) ni o jẹ Baba Ẹgbẹ na, yio dara pupọ bi awọn Ijẹṣa Minna ba le da Ẹgbẹ na silẹ, ajọ a kun o.

### IJỌ ỌMỌ IBILẸ *U.N.A. CHURCH* MINNA.

Ni ọjọ *Sunday* ijọ karun oṣu *July* 5/7/25 awọn Ijọ Ọmọ Ibilẹ ṣe akanṣe Iwasu ti Oloyinbo, ni agogo mẹrin ọsan 4 p.m. Ọgbẹni C. Kanawa Paul baba Ijọ na a-ji-sọ didun loyinbo, ọkunrin kọkọbọtọ on ni o wasu, o sọ igilangọ Gẹsi ni ọjọ na e yan ọrọ iwasu rẹ lati inu Iwe Mimọ, Luku ori karun ẹsẹ kẹdọgbọn "awa ri emọ loni" ọrọ rẹ wọ enia lọkan ṣinṣin, eyi to dun mọ awa ti ko gbọ Oyinbo ni Kọnkọbiliti, Irẹsipọnsibiliti. Bẹ na si ni Ọgbẹni Marcus Thomas, Eleti-ọfẹ ninu Gẹsi, on ni o ṣe itumọ rẹ fun wa, o si wọ ni leti ṣinṣin awọn enia ti o wa si ibi Ẹsin na pọ diẹ ki Ọlọrun ki o ran Ijọ Ọmọ Ibilẹ lọwọ ki o le ma dagba ninu ifẹ Kristi Jesu. *Amin.*

### OJO RỌ K'ILẸ TUTU.

A dupẹ fun ojo ti Baba Ọrun fun wa ni ọdun yi, ojo na nrọ daradara, a si ngbadun rẹ, ki Baba rọ ojo ibukun fun wa o. *Amin.*

### ẸRANKO BUBURU IKORIKO (*WOLF*)
### IKORIKO—A-BIJA-WUKẸ.

! Ojojumọ ni a nkiyesi orişirişi jamba ti Ikoriko nṣe ni oru nigbati gbogbo enia ba ti sun tan, o pa Aja ọrẹ wa kan o si goe lọ bambam bẹni Tolotolo ko niye ti o nwọle gbelọ pẹlu ija wukẹ rẹ njẹ mo bere tani o jẹbi, bikoṣe awa papa ti a wa ati jẹun wa si ilu Ikoriko. Ki Ọlọrun ko fi ofo ra ẹmi, ki o si ṣọ gbogbo wa ni ilu Ikoriko ki a le pada de ile wa ni alafia.

### IKORIKO JOKUJOKU.

Ni ibi isinku awọn Imale ati ti awọn Keferi, a ri ọpọlọpọ oku ti Ikoriko hu jade, ti o si jẹ ajẹti aç sibẹ, eyi jẹ ki a kin awọn ẹgbọn wa ti nwọn nsọrọ sinu iwe *Eko Akete* pe ki nwọn su oku (*to consign the dead to flames*) o ṣe anfani ki Ikoriko hu oku enia wa jẹ lọ. O daju pe Ikoriko ko le jẹ eru, bẹni idin ko le jẹ eru, bẹni ilẹ k le jẹ eru.

Eru wa titi fun ẹri titi lailai, ti a ba fi pamọ si Igo, ero ọgbọn ijinlẹ ni eyi, yio si jẹ ohun ti ya nira fun Yoruba lati ṣe nitori igbagbọ wọn ni p enia ti inu aiye wọ ina. Ki Ọlọrun majẹ ki a w ina ni ọrun. *Amin.*

Emi ni tiyin nitotọ,
BUBUYEH.

---

# NOTICE.

*In the matter of the estate of*

**ANDRE SALAKO**

(DECEASED).

*Pursuant to an Act of Parliament made and passed in the 22nd and 23rd years of the reign of Her late Majesty Queen Victoria Chapter 35, intituled, "AN ACT to further amend the law of Property, and to relieve Trustees."*

NOTICE IS HEREBY GIVEN that all persons having any claims or demands upon or against the estate of Andre Salako late of 30, Campbell Street, Lagos, in the Colony of Nigeria, who died at Agweh in the French Colony of Dahomey, intestate, on the 30th day of December, 1924, and Letters of Administration of whose personal estate and effects were, on the 26th day of June, 1925, granted by the Supreme Court of Nigeria aforesaid to Joao Salako Andre and Albert Salako Andre (two of the children of the said deceased) are hereby required to send in writing, particulars of their claims or demands to the said Joao Salako Andre and Albert Salako Andre at their residence, 30, Campbell Street, Lagos, aforesaid on or before the 30th day of September, 1925, after which day the said Administrators will proceed to distribute the assets of the said intestate among the parties entitled thereto, having regard only to the claims and demands of which they shall then have had notice, and that they will not be answerable or liable for the assets or any part thereof so distributed to any person or persons of whose claim or demand the said Administrators shall then have had notice.

AND ALL PERSONS indebted to the said estate are hereby requested to make immediate payment accordingly.

Dated at Lagos, this 1st day of July, 1925.

J. S. ANDRE,
A. S. ANDRE,
*Administrators.*

---

**Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street, begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!**

GUARANTEED

THE RALEIGH

FOR EVER



# RALEIGH

## THE ALL-STEEL BICYCLE

## MILLER BROS. (L'pool) LTD., LAGOS.

## EKO AKETE

EKO, SATURDAY, JULY 18, 1925.

B'O R'OYEKAN, O R'ỌBA O,
B'O R'OYEKAN, O R'ỌBA O,
DOSUMU 'O KU, ONIYE,
DOSUMU 'O KU, ARA LO FI TI,
B'O R'OYEKAN, O R'ỌBA O,

Ranyinranyin bi agbayun kọ ni kikọ orin yi dun bi, l'Eko igbani, nigbati Ọba Ọyekan, (Kabiyesi, Ọrun 're) fi rọpo Baba rẹ, o ṣe! Ọkunrin lọ!

Ṣẹlẹrú, Ojo kò p'oke ko ṣẹgbẹ okítì,
Ẹgbẹ baba wọn ni i ṣe.

Ọrun oni a sãn: gẹgẹ bi a ti nkọ orin yi nigbana, ti ilu kẹrikẹri nsọ tẹnu rẹ, ti ilẹkẹ nsọwọ̀wọ̀, Ha! Sala, Agbekẹ, õ gbọ kikun ilu na ndan?

Iji iji, iji kẹ-nji,
Iji kẹ-nji, kẹ-nji, kẹ-nji, kẹ̀kẹ̀ji!

Bẹ si ni o yẹ ki a ṣeranti kikọ rẹ lode oni: talo ma ri awọn Oloye wa Onifila-funfun jakejado igboro ilẹ yi, ti ki yio kọ́ lala wipe A! Ọba lo nlọ yi, Eleko lo nlọ yi! Ko dede ti eyi fi nri bẹ: gẹgẹ bi a ti npe awọn Gomina ni aṣoju Ọba *King* (Kabiyesi, Alaiyeluwa!) bẹ̄ gẹgẹ ni awọn Ijoye wa jẹ Aṣoju Ọba Eleko nitori ọla alamu ni adiẹ fi nmu'mi l'agbada, ẹmi abata lo nm'odo ṣan, ọla baba lo nmu ọmọ̃ yan. Idile kan iba fi ẹnikan joye Onifila-funfun tabi Abagbọn bi afo irufẹ oye bẹ ba ṣeṣi ṣi paya silẹ ni idile na ni igboro Eko, ti ko ba fi ti Eleko ṣe, nipa pe ki Olowo lọwọ ninu irufẹ oye bẹ, tabi nipa dide fila fun Oluwarẹ, Agbẹdọ! Oye ẹlẹmu-loke-Apapa ni oye irufẹ ẹni bẹ.

O si jẹ ohun to dun mọ ni gidigidi pe Ijọba Gẹsi ki ṣalaika irufẹ oye bẹ si: lọ si Ganran, lọ si Munisiba, lọ si Ile-Ọba *(Government House)* irufẹ iyẹsi ati igẹ̀si bẹ ko pada nijọkan-abọ: awọn Oloye Onifila-funfun wo lo gba Arẹmọ Ọba *King* lọwọ nijọun bikoṣe awọn Oloye wa: kosi ẹniti ọla bayi ko wu lori.

Ṣugbọn ni Eko tiwa oni nkọ o? lati igbati Ijọba ti sọ pe awọn Oloye wa ti ṣe laifi si wọn kọ ni ọrọ na ti sor ilu kodo? nitotọ a gbiyanju lati sọpe ki awọn Baba wa na lọ ṣe "tó" lọdọ Ijọba, eyini ni pe ki nwọn lọ tọrọ aforij laifi na, ṣugbọn nigbati o dabi ẹnipe nwọn ko ri si ọrọ wa nkọ, o ha yẹ ki ẹyin ilu dakẹ bi? ani o ha yẹ ki ẹnyin Ilu joye Abata ta kete bi ẹnipe ko b'odo tan tabi o yẹ ki ẹ wa nipo Adiro fẹhinti, o nwo'ṣe idana? O d'odi! A ṣebi nigbat igbi aiye kọlu Ọgbẹni wa Aṣọgbọn Oloye Olundẹgun ni ọdun kejila tabi kọkanla sẹhin, ti Ọba Eleko fi gba a ni fila nipa iwa ti Olowo sọ pe o hu si on, a ṣebi lọgan, ati bi adiẹ-ko-sọ'ka ni awọn Ọmọ-Ọba ati awọn Agbagba ilu wa yi kanna san ṣokoto giri, ti awọn obinrin si tun ikolobo wọn pọn; nwọn ko sun asun maparada ti-igi-aja ṣugbọn nwọn ṣe guduguḍu meje, nwọn si sa ipa wọn de gongo, ki ọrọ na to di akanti, ti arẹ si ti mu oni-seida titi di arọ ọjọ oni bo ba dabi irọ, ẹda iwe ti awọn Sanmari wa na kọ si Igbakẹta-Ọba *(Administrator)* nigbana leyi lede Gẹsi, iwe eyiti awọn Isọri-isọri awọn Ọmọ-Ọba fọwọ si:—

The Illiterate Office,
Docemo Street, Lagos
7th April, 1914.

Sir,

We the undersigned princes and others representing portion of the Community of Lagos hereby most earnestly and respectfully beg to approach the Government through you in manner hereinafter following:—

That seriously regretful of the existing misunderstanding between Prince Eleko and the Ex-Chief Ashogbon of Lagos which unfortunately resulted in the deposition of the latter x x x x x x x x

That in this connection we had several interviews with the Prince, at which we humbly supplicated him for pardon on behalf of the deposed Chief.

That the Prince ultimately expressed himself to us as follows, that the Government is his main supporter and protector from the date of his appointment as the Head of the Royal Family of Lagos till to-day, and seriously considering the timely assistance rendered to him whereby the defiant propensity of the deposed Chief was effectively curbed and a serious crisis averted, he feels powerless to yield to our untiring request for reconciliation but counselled to approach the Government in the matter and that the reconciliation depends solely on the Government's consideration. Hence the need of hereby most humbly

[ap]proaching the Government is, that it may be graciously [pl]eased to adopt such steps as would lead to the reconciliation of both parties, and in mercy to pardon the deposed [ch]ief whom we have every reason to think is seriously [sm]arting under remorse of conscience and is penitentially [im]pelled to sue for Pardon and Forgiveness at the hands of [bo]th the Government and His Highness Prince Eleko.

Awaiting your very kind reply,

We have the honour to be,

Sir,

Your Obedient humble Servants

| | their |
|---|---|
| Prince Yesufu Oba | X |
| Prince Yesufu Dosumu | X |
| Prince Fadeyi Dosumu | X |
| Prince Falolu Dosumu | X |
| (Sgd) Prince Odunsi Attin | marks |

| | their |
|---|---|
| Princess Talabi Erelu | X |
| Hanidu Iginla | X |
| Princess Fashola Iji | X |
| Bakare Ajakaye | X |
| Fatade Tokosi | X |
| Asani Giwa | X |
| Talabi Atitebi | X |
| Tairu Otun | X |
| Kasumu Akeolu | X |
| Jeboda Akiolu | X |
| Seidu Akiolu | X |
| Adamc Ofun | X |
| Princess Alimotu | X |
| Bashorun Savage | X |
| Thomas Seriki | X |
| Awere Dosumu | X |
| Sufianu Dosumu | X |
| Amboja Dosumu | X |
| | marks |

For ourselves and others
Equally interested.

To His Honour
The Administrator
LAGOS.

Bakanna ni a si ri pe o yẹ ki ẹnyin Alagba ti ẹnu nyin to'lẹ ni'lu, ẹnyin Ẹgbẹ Bombata (Dẹmọ) ẹnyin Ẹgbẹ Òdòdó *Nigeria (Union of Young Nigerians)*, ẹnyin Ẹgbẹ Debi *(The People's Union)* ẹnyin Ẹgbẹ *Ansar-ud-deen* ti kekere t'agba, ẹnyin Ẹgbẹ Khilla ẹ wa wọrọkọ fi ṣ'ada lati ṣe ipade larin nyin niyatọ fun fifi egungun otolo to ọrọ awọn Oloye wa wọnyi lọdọ Ijọba (eyi ki i ṣe pe a nsọ ti gbun-gbun-gbun ti nwọn ṣi ni si Aṣoju o, ẹla lọrọ) bi a o tilẹ pada wa b'adiẹ, o yẹ ki a le Akata jinna na, eyini nipe b'ao tilẹ wa sọ ti laifi ti nwọn sọpe Aṣoju fi lọ wọn; o tọ gidigidi ki a kọkọ ṣatunṣe ipo wọn pẹlu Ijọba na.

Ẹ jare ẹ maṣe wipe kini a tun nsọ yi ẹwẹ, gẹrẹjẹ la nba agba: o yẹ ki a ba awọn Oloye wa nipo wọn: ko si ohun ti oju ko ri ri: nitorina la ṣe tun sọ ọrọ yi lati fi ji ẹnyin Agbagba ilu giri: a ki nri a-rẹ-maja: ahọn pẹlu ẹnu nja, ambọsibọsi awa ọmọ Anọbi Adamọ.

Ninu eyiti Gomina Adele t'ajo bọ yi, ẹ jare, ẹ mu ọrọ yi ni kankan-ṣi. Ọbangiji Ọba-Ogo yio si gbọwọ nyin karikari. A! Ẹnyin Agba Ilu, Ẹ ko gbọ ohun-ipe Anọbi Isa *(The Master Jesus)* bi o ti nkọ lala si nyin lati isalu-ọrun, nitori ọrọ awọn Baba wa wọnyi, A! Ẹ gbọ, Ohun na lo nsan bi Ara yi.

Ye e, ẹ wo bi Ọrun ti nkọ yẹri ti gbogbo ilẹ si mì tìtì. Ye e, Ye e, Ohun na leyi.

"Alabukunfun ni Ẹnyin Onilaja,
Nitori Ọmọ Ọlọrun la o ma pe nyin."

---

## "EKO AKETE"

ATI

## ATARI AJANAKU.

[*Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

**Mo bẹrẹ f'oji,**

Ki a to bẹrẹ si ọrọ lati sọ, a o kọkọ tọrọ gafara lati ki awọn ọkawe wa wipe, ko to ọjọ mẹta baun? Nitoripe "idiwọ diẹ" gẹgẹ bi Oniwe-irohin "Eko Akete" ti pe e, ko jẹ ki a ṣe wosika sinu Iwe rẹ ti ọsẹ ti o kọja. Lati iwọn ọdun meji tabi ju bẹ lọ diẹ, ti a ti ni anfani lati ma kọ iwe si "Eko Akete," ko da ni loju wipe Iwe-irohin na jade lẹkan ri lati igbana, laisi wosika wa nibẹ. Ko si si ohun meji ti o tubọ mu sababi aijade ti ọsẹ ti o kọja wa ju inira ati bi ọjọ melo yi wa, ti a nri ninu "oju'le" tabi yara kan ti a haya lọwọ "Eko Akete" ninu "Agbole" rẹ.

Ko nṣe wipe Oniwe-irohin "Eko Akete" lo ni ile ti a ngbe, a ko si haya ile gbe, de ipo ti a o fi haya lọwọ Oniwe-irohin "Eko Akete;" ṣugbọn itumọ ọrọ ti a sọ ni wipe, gbogbo Oniwe-irohin lo dabi Onile *(Landlords,)* Iwe-irohin wọn si ni "Agbole" *(Compound,)* gbogbo awa ti a si nko iwe si Iwe-irohin wọn ni ọsọsẹ, ati gbogbo enia ti o npolowo *(advertize)* ọja tita sibẹ, ni o wa nipo ẹniti o haya ile lọwọ wọn *(Tenants.)* Nitorina, gẹgẹ bi ẹniti o haya ile, a ko l'ẹnu lati paṣẹ fun

Onile, şugbọn ti Onile ba nni wa lara ju, a mọ ohun ti a le şe. Gẹgẹ bi ọpọlọpọ enia ti mọ wipe "Atari-Ajanaku" ko nşe ẹru ọmọde; a dupẹ wipe Oniwe-irohin "Eko Akete" fi aye nla silẹ fun wa ninu "Agbole" ti a haya lọwọ rẹ, on papa fi ọwọ mu apakan ibiti o wa, ko si si gbọn'mi si i, omi ko to o, kan ri larin wa, afi ni lọlọ yi, ni asiko ti "Kekere Ilu" wa haya ojule kan nitosi ibiti awa ngbe ninu "Agbole" "Eko Akete," ti "Kekere Ilu" si fẹ mọ oju Onile tabi Megida, bi aşa awọn Gambari, ju awa ti o ba pẹlu rẹ nile lọ.

"Kekere Ilu" mu oşuka, o ni on fẹ gbe "Atari-Ajanaku" ru, njẹ bi Ajanaku ba binu nkọ o, ki yio ba di ogun Itakun ti o ni ki Erin ma goke alọ? Bẹni ko dara ki a gbọ ija awa pẹlu "Kekere Ilu" nitori awa mejeji jọ haya ojule kọkan gbe lọwọ "Eko Akete" ni, o si tun buru ẹwẹ, lati gbọ wipe, Atari Ajanaku pẹlu Megida papa nja; şugbọn bi Megida wa oninu-rere, Megida wa ọkunrin jẹjẹ, ab'ija kunkan, Megida wa ti o ti nfi Iwe-irohin rẹ "Eko Akete" ja fun ire ilu laibẹru ati laişe ojusaju ẹnikẹni lati igbati o ti bẹrẹ rẹ ni ọdun kẹta, ba to idayi ti o jẹ ki awọn ọlọtẹ ko ba on, ti o jẹ ki awọn ọlọtẹ şi on l'ọna, ti o si fi aye silẹ fun awọn ọlọtẹ lati purọ fun on, Atari Ajanaku yio ba Megida fi pẹki kan pẹki.

Bi ọmọde ba şubu, a wo iwaju, bi agbalagba ba şubu, a wo ẹhin. A ko le şẹşẹ'sọ wipe "ọmọ kekere" ni *Professor* Deniga jẹ lọdọ wa; şugbọn sibẹ, nigbati a b'oju wo ẹhin, ti a ri işẹ ti o ti şe, papa gbogbo *lectures* awiye rẹ lori awọn Enia Dudu agbagba ilu, ologbe ati alaye, *African Leaders past and present.* Iwe *Nigerian Who is Who* ti o nşe, wosika ti o ti nşe sinu Iwe-irohin miran ri ni ilẹ yi ni ede Oyinbo, ki o to da Iwe-irohin tirẹ papa silẹ l'ẹnu ọjọ mẹta yi, ayan ati akikanju rẹ si ọrọ ilu, ani, nigbati a ba ranti aşeyẹ nla ti *Professor* Deniga Oniwe-irohin "Eko Akete" şe pẹlu awọn ẹgbẹ *Remingtonian* ti o kojọ ni akoko na şe fun Makọli nigbati Kiniun Onibudo yi jare ilẹ Apapa bọ Ilu Oyinbo fun Oloye Oluwa, ati ọrọ işiri nlanla ti o sọ nipasẹ Makọli ni *Imperial Hotel*, eyiti nwọn tẹ sinu Iwe ti a npe ni *The Remmingtonians and Herbert Macaulay, Esq., C.E.*, ati aşeyẹ nla ti o tun şe nigbati Makọli kanna yi di ẹni ọgọta ẹdun ni ẹdun ti o koja, ati eyiti o tun le şe nigbati Makọli ba di ẹni ọgọrin ọdun ni *November 14, 1944* l'agbara Baba, nigbati Ọgbẹni Deniga papa yio di ẹni ọdun mẹrinle-lọgọta; ti a ba ranti wipe lakoko kan, ti *Our Great Horatio* Jakisini lọ si Ilu Oyinbo, Ọgbẹni Deniga lo nşe Iwe-irohin rẹ *Lagos Weekly Record* kanna yi titi o fi pada de; ti a ba si ranti itu nla ti o ti fi Iwe-irohin rẹ "Eko Akete" pa fun ire ilu pẹlu agbara Ọlọrun ati agbara awọn agbagba ti o wa l'abẹlẹ, nitori ọpọlọpọ işẹ rere bayi ti Ọgbẹni Deniga ti şe sẹhin lo jẹ ki a şi fi suru haya "ile" gbe lọwọ Iwe-irohin rẹ titi di ọni, a si tanma wipe ki yio fi inira tabi wahala, tabi irọ awọn ọlọtẹ le wa jade kuro ni sabongeri ti o yọda fun wa ni Agbole rẹ l'ọsọsẹ lati iwọn ọdun sẹhin. Adura wa ni wipe ki Oluwa ki o da ninu, ki O pa'na ọtẹ run, ki O lọra ẹmi gb ẹniti o nfẹ ire ilẹ yi, ki O ma si şe jẹ ki eb awọn ọlọtẹ ku titi ilu Eko yi yio fi toro loju ki nwọn to ba Mọliki ọba ina lọ si ẹrun a lati j'ere işẹ ọtẹ, işẹ darudapọ ati işẹ arijẹ nin ilu, ti nwọn şe l'aiye.

## ABỌ O, AROLE GOMINA.

Pẹlu itara pupọ ni a ti nreti bibọ Arole Gom ki a to gbọ wipe o de ni *Tuesday* Atalata ija nitorina, tayọtayọ ni a fi ki i kabọ. Ninu gb Oyinbo Onişẹ Ọba ti o wa nilẹ yi loni, ko si ẹniti o şe wa ninu wọn to anu Arole Gomina, F. M. Baddeley, C.M.G., nitori ogun buruku (*estate*) ti Ọlọla Hugh Clifford fi silẹ fun u la nipasẹ ọrọ Eleko, ati "Şọlọ" ti ọlọtẹ nfẹ t'ow bọ nisisiyi, nipasẹ Ọba Yesufu Adewọlẹ ati ti Akinşemọyin ti nwọn fẹ fi Ibikunle Fasinro toye jẹ.

George Iyitọla Oyekan jẹ ọkan ninu a mọkọndi-logun ti o kọ iwe si Eleko wipe ki o kuro ni Iga; şugbọn nisisiyi, o ti k'abamọ Iwe-irohin mẹta tabi mẹrin wipe aşişe ni on nitorina, nwọn ku mejidi-logun. Ibaşe wipe a mejidi-logun wọnyi ko daba lati le Eleko jade k ni Afin (*Palace*) rẹ larin ọjọ mẹrinla, ki o jẹ w nwọn kọn şa ara wọn jọ, nwọn da ẹgbẹ silẹ ara wọn, ki nwọn si fi Ibikunle Akitoye jẹ Ba ẹgbẹ na; nigbakugba ti nwọn ba si fẹ şe ere, nwọn tẹ itafo si gbangba Ita Balogun ni o, tabi *Entertainment* ni *Glover Memorial Hall*, Ile-ẹ ni Ẹhingbẹti, ti nwọn si ya Ade (*Crown*) oai- ti "Orlando Furioso" fi şe ere Ọba Belşesa fu ti nwọn si fun u ni orukọ nla bi "*King* Ak mọyin-wọlẹ, eyini ni, apakan Akitoye, apa Akinşemọyin, apakan Adewọlẹ, "Akito-mọ wọlẹ" tabi Akitoye ti o pọn s'ẹhin Akinşemọ ti Adewọlẹ si gbe awọn mejeji wọ ile lọ; ẹnik ki ba ti wi ohunkohun: kaka bẹ, ti nwọn ba wa si ibi ere na, ti Ibikunle Akitoye si gunwa aga ti nwọn ba ya lọwọ "Enia Şoro," ti aw mẹtadi-logun ọmọlẹhin rẹ ba si wipẹ, "Kabiy ọmọ Fasinro ju wọn lọ," tayọtayọ ni a ba fi dab wipe, "Lọpọlọpọ." Şugbọn aba ti awọn mẹta logun da lati fi jẹ Ọba gbogbo ilu, lọna ti o lod ifẹ gbogbo Oloye, ti o lodi si ifẹ ọpọlọpọ aw ọmọ Ọba, ti o lodi si ifẹ ilu, buru, o si b'ogiri pẹ

A ko sọ eyi pẹlu inunibini tabi arankan Ibikunle, nitoripe ko şẹ wa ni ẹşẹ kan ju ohun (*instrument*) ti o fẹ fi ara rẹ şe lọwọ awọn ọlọ ti o fẹ ki Ibi-fọ-'le Dosumu.

Idi rẹ ti a fi wipe anu Ọlọla F. M. Baddeley wa pupọ ni wipe, alejo ni Arole Gomina yi nşe arin wa. Eyiti gbogbo ilu iba si fi wa ni ala pẹlu irẹpọ labẹ Ijọba rẹ titi a o fi ni Gomina tit miran; ninu hilahilo ni awọn ọlọtẹ fẹ ko Ijọ Baddeley si, nwọn fẹ ki o kuro ni Arole Gomina

Asoju Ọba ( *King*, ) ki o di "Arole Ikoko ti nṣoro bi Agbọn ;" nitori ko si Arole Ọba kan, ti o mọ iyi Ọba, (i o jẹ lọwọ ninu Ọba ti enia mẹtadi-logun pere daba lati fi jẹ larin ilu ti a le ka enia ti o le ni ẹgberun ọna mọkandilọgọrun, (*over 99,000 people*) afi ti Arole na ba kuro ni Arole Ọba, ki o si di Arole Ikôko ti nṣoro bi Agbọn.

Nitorina, nigbakigba ti nwọn ba mu ọrọ Ibikunle Akitoye de iwaju Arole Gomina, imọran ti ao fi tọwọ-tọwọ (*respectfully*) gba a ni pe. ki o bere gbolohun ọrọ mẹsan lọwọ Yesufu ọba ati awọn Abẹyọ rẹ.

Ekini :—Bi enia mẹtadilogun pere lo fi Eṣugbayi jẹ Ọba Eko ni ọdun kẹdọgbọn, tabi enia mejidi-logun lo fi baba nla Yesufu Adewọle papa Ologun Kutere jẹ ni ọdun kẹrindilọgọsan ọhun.

Ekeji :—Nigbati nwọn da ọjọ mẹrinla fun Eleko lati kuro n'Iga, nibo ni nwọn fẹ ki o lọ pẹlu gbogbo Ile rẹ, tabi nwọn fẹ ki o ko lọ si Ile Ibikunle Akitoye ni ?

Ẹkẹta :—Ni eyiti Yesufu nṣe fãri pe on lo mu *Prince* Eṣugbayi lọ sọdọ Gomina ni ọdun kẹdọgbọn ọhun yi, o fa a l'apa ṣ), o ni ko niṣo nile Gomina ni, tabi awọn ọmọ ọba, ati Ijoye ati Ilu lo kọkọ parapọ yan Eṣugbayi ni Eleko tan, ki on to mu u tọ Gomina lọ ?

Ẹkẹrin :—Ki gbogbo awọn to fi ọwọ siwe ati Lọya Akinṣemọyin wa p'itan bi nwọn ti ṣe ba ọba tan lati mọ ojulowo ọmọ yatọ si "ọmọ Agarawu" ninu wọn.

Ẹkarun :—Pe ti ko ba si aiye Oyinbo, ẹnikan le kọ iru iwe ti awọn mọkàndilogun kọ si Eleko yẹn ko ma di ijọgbọn si wọn l'ọrun ?

Ẹkẹfa :—Bi otitọ ni tabi otitọ kọ ni itan wọn to wa ninu iwe irohin *The Lagos Weekly Record* ni lọlọyi ?

Ekeje :—Bi alafia tabi whala ni nwọn nwa nilu, tabi idarudapọ ni ọna ti nwọn le fi ran Ijọba lowọ ?

Ẹkẹjọ :—Bi nwọn fi àbá ti nwọn da lati le Eleko jade yi lọ oloye Ọbanikoro tabi wọn ko fi lọ ọ ; ti nwọn ba fi lọ o, njẹ imọran wo lo fun wọn ?

Ẹkẹsan :—Ki o bere lọwọ Ibikunle Akitoye papa bi o ba ti ranṣẹ ẹwu oye, ilẹkẹ, ati ade lọdọ Oyinbo M. Nathan & Co, ati iye enia melo lo nfẹ ki Ijọba ba on walọ (*deport*) kuro n'ilu n'ijọ *Coronation*, Iwuye rẹ ni iranti ọjọ na ?

Lẹhin ti o ba ri idahun gba si ibere mẹṣẹsan yi tan, ki o wa f'esi fun wọn pe *I am sorry, gentlemen, nothing doing ; off you go ! ! !*

Lẹhinna, ki Arole Gomina jọwọ ba wa tun ọrọ awọn Onifila-funfun ṣe ati ọrọ Eleko, ki o jọwọ nitori Ọlọrun ki o si ba wa fi Eleko s'ipo ọba rẹ pada.

Nitotọ ni awọn ọlọtẹ ti Gomina Clifford ni itikuti, nitotọ ni Gomina da Eleko duro lati tẹ ifẹ awọn ti ko tiju lati pe ara wọn ni "Enia lasan" *Contemptible gang* lọrun, ṣugbọn ọlọla Hugh Clifford ti wa, o ti lọ ; loni, o si ku on pẹlu ẹri ọkan rẹ (*conscience*) nipasẹ ọrọ Eleko.

Bi Ọlọla Hugh Clifford ba kọ lati fi Eleko si ipo rẹ pada titi o fi lọ, iyẹn ko wipe ki Ọlọlọ F. M. Baddeley maṣe ṣ'anu Eleko, odidi Ọba. Nigbati Gomina Lugard na owo iyebiye si Kaduna to ni on fẹ fi ibẹ ṣe Olu Ilu (*Capital*) gbogbo *Nigeria*, nigbati Ọlọla Hugh Clifford de nkọ, ko wipe Ijanu ni Lugard njẹ ? Igbimọ *Nigerian Council* ti Lugard da silẹ nkọ ? Gomina Clifford ko ha sọ di oku, ko ha si fi Igbimọ miran rọ'po rẹ ?

Bẹ gẹgẹ ni Ọlọla F. M. Baddeley le yi ifẹ Clifford pada si rere nipasẹ ọrọ Eleko, nitorina a bẹ ẹ, a tun tun un bẹ, ki o fi Ade Ilu ti Ọlọla Hugh Clifford ti ṣi kuro lati ọdun karun Oyinbo de wa lori pada. *Amin* ! Bẹni ki o ri ! !

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

### THE EDITOR'S OBSERVATORY.

#### Men of God in Court. !

Such was our ejaculation, when in the morning of Thursday last, the 16th instant between 10 and 11 of the cloch, we espied few "Tects" with apparently one on a bike leading the way to the Central Police Station on the arrest of the Rev, Joshua A. Leigh of 8, Pike Street, Lafiaji, Lagos at the instance, it appears, of the Bishop of Lagos on the alleged charge stated hereunder :—

1313/25. Police *versus* Rev. J. A. Leigh.

Publishing defamatory matter to wit, anonymous, letters written and posted to Bishop Melville Jones with intent to falsely defame his character during the month of June, 1025. Section 375, Vol. 1, Chapter 21, *Laws of Nigeria.*

The case, we learn, will be proceeded with next Monday, in the Police Magistrate's Court, with the Solicitor-general prosecuting, according to the information which has reached us.

---

ONINI BABA ẸWU.

Ọgbẹni D. L. Oshodi ti 36, Idoluwo *Street Lagos* ni oriṣiriṣi *Ivory Coat & Trouser button* ( Onini ) fun tita kosi aṣọ ti ko ni *button* to yẹ̄. O si ni wabi-wọsi ero-ija *Tailor* ( *Tailors Trimmings* ) ni tita bakanna ; o si nfa'ṣọ ṣe *button* ( *Press Coat Buttons* ) ki awọn af'aṣọ-dara ( *Expert Tailors* ) maṣe jafara lati ba ra tiwọn ; ọpọku-ọyọku ni ọja meremere wọnyi.

TO LEASE.

A land, area 110 square feet at Ọtọ Island.

Apply to the EDITOR

## ISỌKUSỌ *ELETI-OFE.*

Si Oniwe Irohn *Eko Akete,*

Alagba.

Ninu iwe irohin *Eleti-Ọfẹ* ti *Wednesday July* 15th 1925 ọpọlọpọ isọkusọ ni mo ri ka nibẹ, eyi ko si ya mi lẹnu arara, nitoripe ni ọpọlọpọ igba miran ti mba fẹ lati ri bi ṣokeṣodo enia ati bi ẹniti o lojo ju akata lọ ti nfi ara rẹ ṣe yẹyẹ, nko nṣe wahala kan kiri mọ ti nba sa ti ri *Eleti-Ọfẹ*, ng o ri gbogbo nkan ti mo nfẹ nibẹ.

Ki nṣe Oliver Holmes arara bikoṣe Ọgbẹni E. A. Akitan to ka ara rẹ kun ọkan ninu awọn oniwe irohin Eko lo sọ ọrọ omugọ yi sinu *Eleti-Ọfẹ* rẹ ti ijẹrin pe "maṣe duro soju kan, sa ma sọ otitọ, tabi maṣe tẹ sọtun ma si ṣe tẹ sosi ṣugbọn sa ma sọ otitọ." Itumọ ọrọ Oliver Holmes yatọ si eyi patapata, ṣugbọn Awobọ Dawọnru ti apele rẹ njẹ E. A. Akitan lo da ọrọ na ru patapata gẹgẹ bi Dawọnru orukọ rẹ. Ibaṣepe lakaye to oniwe-irohin *Eleti-Ọfẹ* ni, iba mọ pe on kọ lo sọrọ, ọrọ lo gbe on papa sọ, nigbati o wi pe ki enia "maṣe duro soju kan, lẹsẹkanna to si tun wipe ki oluwarẹ maṣe tẹ sọtun tabi osi" Ewo ni ki oluwarẹ ṣe nigbana, ṣe ki o fo soke bi ẹniti akọ warapa nba ja ni, tabi ki o ma fi siwaju fi sẹhin bi ṣokeṣodo ni, nigbati ko gbọdọ duro jẹjẹ soju kan, ti ko si gbọdọ tẹ sọtun tabi sosi gẹgẹ bi ikilọ omugọ *Eleti-Ọfẹ*? Bi enia ko ba tẹ sọtun tabi sosi, o duro soju kan niyẹn, ṣugbọn Ọgbẹni Akitan ni oluwarẹ ko tun gbọdọ duro soju kan. Nwọn ni apẹrẹ san ju ọrọ ẹnu lasan lọ, nitorina inu mi yio dun pupọ bi oniwe-irohin *Eleti-Ọfẹ* ba le kede ninu iwe irohin rẹ ti ọsẹ to mbọ lati pero iworan pẹlu enia papa ki o si fun wa ni ọjọ kan ti a le wa wo iran bi Ọgbẹni Akitan papa ti ṣe le duro ni gbangba ọkọkan tabi odẹdẹ ibi iṣẹ rẹ ni *13, Victoria Road*, ki o ma tẹ sọtun, ki o ma tẹ sosi, ki o ma si ṣe duro loju kan nigbana ni emi yio mọ pe otitọ ni o to lati jo ijo iya ka wo, pala ṣigi ṣan ṣan ṣan.

Gẹgẹ bi ọmọ ti tan lara ọmọ to njẹ eru, bẹ gẹgẹ ni ko si anfani kan arara mọ lara oniwe-irohin to wipe on ki yio duro soju kan ki on to ṣe otitọ. Oju kan ni ada nni. Oju kan ni otitọ ni, otitọ ko ni oju meji, ẹnikẹni to ba si fẹ ṣe otitọ o ni lati duro soju kan ti otitọ wa. Ti o ba yẹ ni iwọsi ọkọ ero, irufẹ Awobọ Dawọnru iyẹn wipe on wa bi alala larin Ilu ati Ijọba, on o si ma sa ipa on gẹgẹ bi atẹhinwa lati maṣe tẹ sapakan ṣugbọn lati ma sọ otitọ. Irufẹ "otitọ" to sọ fun Mọlufọdi lakoko Idibo, iru alaisotọ otitọ ti *Agbaosi* sọ si Makọli lara ninu *Eleti-Ọfẹ* ti *May* 6, irufẹ irọ nlanla ti *Scrutator* pa to pe ni otitọ sinu *Eleti-Ọfẹ* ti oṣu to kọja bi nkan, nigbati o wipe Makọli ti yọ gbogbo ororo ara Imale Eko tan, (Makọli olore Ilu) ati oniruru irọ miran ti *Eleti-Ọfẹ* npe ni otitọ. A wi tan oni "ọkọnrin Oṣelu olokiki kan lo sọ fun on nijọkan pe, bi on ba ri nkankan ti ko dara nip[a] Ilu, ki on ṣebi ẹnipe on ko ri i." Irọ patapata [n]i eyi bi bẹkọ, ki Ọgbẹni Akitan darukọ Oṣelu ol[o]kiki to ba sọ irufẹ ọrọ bẹ. Ṣiọ, adiẹ op[a] abikupi nka ara rẹ kun adiẹ. Ọlọrun nikan lo m[ọ] bi isọkusọ *Eleti-Ọfẹ* ti dun mi to nigbati o nda[h]un to ndaji nipasẹ ọrọ awọn Oloye pẹlu *Resid[ent]* papa lẹhinti Ọgbẹni Akitan ti gbọ tẹnu Oloy[e] Oluwa tan nipa ebu buruku ti nwọn ni Aṣoju b[u] wọn, ti Akitan si tun pada wi ninu iwe irohin [r]ẹ nibiti o rohin riri ti o ri awọn Oloye si pe "Ti [o] ba jẹ pe otitọ ni Aṣoju bu wọn." Ko mọ pe on [n]i ọgbọn ẹrọ pe awọn Ijoye npurọ niyẹn, nitori[pe] ti o ba gba Oloye Oluwa gbọ nitotọ, o ṣoro ki [o] tun wipe ti o ba jẹ pe otitọ ni ọrọ ti awọn Oloy[e] sọ fun on pe Aṣoju bu wọn. Ẹ ki ngbọ ọrọ afo judi, ọrọ abikọ, akọgbọ, irọ gbigbẹ, ṣokeṣodo a[ti] agabagebe bayi.

Ẹniti o ri Aṣoju ti ko ri awọn Oloye pẹlu b[i] iwa aitọ loju mi. Ṣugbọn Akitan ti ko ri Aṣoj[u] arara, ti o ri awọn Oloye nikan, sibẹsibẹ ti ko [si] gba ọrọ wọn gbọ, ti o tun ni iyemeji si ọrọ ti [o] gbọ lẹnu wọn, on gan ni Ọdalẹ ati ọbaiyejẹ a[ti] Judasi.

Mo rope oniwe irohin *Eko Akete* ki yio wijọ p[e] nipa dida orukọ Mr. Akitan firifiri bayi, mo [ti] npolowo rẹ fun Ilu lati mọ ni, ati pe owo ni e[ni]kẹni to ba polowo ọjakọja yala o dara tabi ko da[ra] sinu *Eko Akete* nsan, nko kọ lati san iye owokow[o] ti ẹ ba bu fun mi le e lori.

Ara Ẹpẹtẹdo le ma ra *Eleti-Ọfẹ* ti nwọn ba fẹ, ṣugbọn awa ara Isalẹ Eko nibi mọ pe nṣe ni iw[e] irohin Awobọ Dawọnru yi nda ọrọ Ilu ru fun w[a] gẹgẹ bi Dawọnru orukọ rẹ.

Emi ni tirẹ nitotọ,

ỌMỌ ỌBA

---

[ Copyright ]

## "EKO AKETA" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

Niwaju Ọlọla Adajọ M. L. Tew.

Ni ọjọ Alamisi ( *Thursday* ) ijọ kẹdogbọn o[ṣu] *June, 12925*.

*Suit No. 215/25.*

ARTHUR RAYMONDSON DAVIES

*versus*

EMANUEL ALAO OJO

Gẹgẹ bi a ti sọ ni ọsẹ to kọja wipe irohin kik[un] yio jade nipa ẹjọ yi lati fi otitọ inu rẹ han, ka ma bọrọ wa bọ :—

Arthur Raymondson Davies bọ sinu apoti o bura Akowe Oba Sekiteriat ni ọdan. On lọ si ibi ijo ni ale ijọ kẹtalelogun oṣu *April* mojumọ ijọ kẹrinlelogun on nbọ lati Bamgboṣe on si ya si ọna titi Ọdunlami si Kotopomoru on si la ṣe Agbako Mọto (*Motor*). Arọ ọjọ na ṣokun nitori ojiji ojo balẹ rururu, kọrọ Kotopomoru yi oṣokunkun biribiri. Mọto yi joko sibẹ ki ṣe wipe o nrin ni, on si ṣubu, o pe si Alao Ojo jade sode lati inu 'le rẹ, o tan ina lẹnkitiriki (*Electric*) rẹ to yoju si ita gbangba, o si bu omi fun on, on si bọju, ṣugbọn ẹjẹ nda ni imu on buruku-buruku lẹhin na on tun gun basikulu (*Bicycle*) on titi on fi ita *Catholic Mission*, nigbati ẹjẹ ko da, ti ailera fẹ ba ẹmi, on kigbe pe Daniel Kayọde, o, Kayọde o o, bẹ ni Kayọde si jade, o wa mu on wa 'le nigbati on de ile, on ranṣẹ fun Dokita Vaughan lọgan Dokita de, Dokita si gbe on sinu Mọto rẹ o di'le rẹ. Jamba yi pọ to bẹ to jẹ pe lẹhin ogunjọ (*20 days*) ni on to le ki ibi iṣẹ on ku atijọ, ti akọkọ pade fun ẹjọ yi, emi ko le wa nitori ẹjẹ yi tun fi oju bode ki jamba to ṣe mi ko si alebu kan lara mi, ṣeṣẹ ni gbogbo enia nyọ mọ mi nitoripe mo dara niba jabale.

Ibere Agbebi :— Nitotọ mo ti gbeyawo, niwọn agogo mẹ: abọ ni jamba yi ṣẹlẹ nijọ kẹrinlelogun oṣu *April*, ita Igboshere ni mo ngbe, ohun to mu mi gba Ọdunlami ni lati sin Ọgbẹni Silva dele nigbati a jade nibijo, otitọ la ya ti Lọya Adeyemọ Alakija, emi ko le sọ bi Ọgbẹni Sila mu *Wine* pupọ, loto mo fi sinu *Motor*, mo dẹ fẹ ri pe o dele, mo gba ita Bamgboshe, lati titi Ọdunlami si kọrọ ti Mọto yi wa, o to iwọn ọgọrin ọpa (*80 yards*) o le ri bẹ ki nto la kọlu, ina baisikulu '(*Bicycle*) mi wa nibẹ ki nto kọlu, emi ko le ri *Motor Car* nitori ojo nrọ, okunkun si ṣu, *Ford Car* ni nitotọ, bi mo ba ri nibẹ mi o ba kọja, mo mu nkan nibi ijo, mo si mu *Champaign*, nịẹ *Champagne* ba ẹ lara mu, *Yes!* Bẹni o ba mi lara mu, mo mu gasi *Champagne* kan niti Alakija. Dokita Vaughan ko ti fi iwe owo ranṣẹ si mi, nitori mi o ti san, o si ntoju mi, Dokita Gray papa ko ti fi ti 'ẹ ranṣẹ gbogbo won lo si ntoju mi, nkan to jẹ ki npe ẹjọ fun ọdun pọnun (*£300*) awọn Lọya mi lo mo iyẹn. Nitotọ mo gbe Igboshere, ki ṣe lati gba ita Campbell ki nba le fi jamba to ṣe mi han.

*Re Examination*—Bo ba jẹ pe lati fi ẹjẹ ara mi han enia ni, mi o ba ri ọgọrọ enia ti nma fi han ki nto de *Catholic Mission Street*. Igo *Champagne* kan ni Lọya Alakija fun awa marun, iyẹn ko si le pa mi, mi o fi Silva sinu *Motor* nitori ara rẹ ko le, ọwọ osi ti mo ni lati gba ni *Motor* yi wa, bo ba wa nibi ẹtọ rẹ ni mi o ba ti kọlu.

Ẹleri kini Dokita Gray bọ sinu apoti o bura. Mo mọ Arthur Davies o pe mi ni ijọ kẹla oṣu *May* o si sọ pẹlu pe Dokita Vaughan lo ntọju on, Igi imu rẹ ṣẹ, o si pin iho imu rẹ si meji, ka ma sọ ti ẹjẹ to nda ni inu rẹ (*Arọkun ẹpo Oyinbo ni yẹn*) titi mo fi wa yẹ wo ni ẹjẹ yi njadẹ, o ba wiwo oju rẹ jẹ, o jẹ ki enia ṣi mọ di ẹ, emi ko le sọ pe o wa sare (*It depends on the speed of his cycling*).

Ibere Lọya Agbebi :—Wọn npe mi la ṣiṣẹ, ẹkan lọgbọn ni mo ngun *Bicycle*, bi wọn pe mi wọ kọrọ ki kọrọ, iyẹn mu bi ‹ jọ ba ti ri, ni ọjọ na dani, boya, ilẹ tutu, ojo nrọ ati ipo ti *Motor* ba wa ni arin ọna, ninu ipalara to ba Arthur, eyiti o ba oju rẹ jẹ wa nibẹ, eyiti ko si le ṣetun ṣe mọ, wa nibẹ, mi o le sọ iye owo mi nisinsinyi nitori mo ntọju rẹ lọwọ—bi mo ba ti ngbọ ibi kan fun ọdun mẹjọ iyẹn ko sọ pe ki *Motor* wa nibẹ fun ọdun mẹjọ. Lọya Thompson ni ki Adajọ yi ọjọ oṣu to wa ninu iwe ipẹjọ si *24th* ki ṣe *23rd of April 1925*.

Ẹleri keji Dokita James Vaughan bura :—Oni-segun Ọpọpo ni *Victoria* ni Eko. Mo mọ Arthur Davies ni Arọ ijọ kẹrinlelogun oṣu *April 1925*. Davies ranṣẹ pe mi, mo ba lori Akete rẹ ninu ile, pẹlu ẹjẹ to da ṣọrọ jade toju timu rẹ, mo gbidanwo lati da duro ṣugbọn ko ṣeṣẹ, mo ni lati gbe lọ sile mi pẹlu *Motor* ti mo mu de bẹ, opo imu rẹ ṣẹ titi de agbekọ to mu iho imu rẹ d‹ni-titi la de isalẹ oju rẹ, ṣugbọn ẹjẹ ti imu rẹ yen papọju, Agodo oju rẹ wu, ehin rẹ meji nmi (Ọlọran lẹmi awọn meji yẹn) gẹgẹ bi mo ti wo ti igi imu rẹ yẹn si, mo gba ni imọran ko pe Dokita Gray ko wa kun mi lọwọ. Ni ijọ kẹrindilogun oṣu *June* imu yi tun pada, ẹjẹ njade ẹnu kẹ tun gborẹjigẹ, ehin meji ti apoti idi wọn yẹ yẹn lo tun da eyi silẹ. "*Ko si orin ta ma kọ si gbẹdu*" afi bi a ba yọ ehin yi kuro, mo gbọ ẹri ti Dokita Gray jẹ, mo si gba gbogbo nkan to sọ gba, mo ri ọpọlọpọ awọn Alayo ri "*Awọn to jẹ pe bi mo ba yọ digba-digba ni kẹ gbe mi*" ṣugbọn mo ri Davies gẹrẹ bi jamba ti ṣe tan, mi o ri oye ayo tabi imuti para lara rẹ ṣaka ni gbogbo ara rẹ ri. Mo ri Alao Ojo lẹhin na.

Ibere Lọya Agbebi :—Mo ri Davies ni nkan agogo mẹta-abọ lọ si mẹrin ni ijọ kẹrinlelogun yi, mo lọ si ibiti jamba ṣe, mo si ri irin ṣoṣoro kan to ṣe jamba yi.

*Court.* Ṣe ki nma gba iwọn yi bi ẹri, ntori mi o gbọ nigba kankan wipe ọti lo fa sababi yi. Mo kuro nibẹ ni agogo marun abọ, *Motor* yi sun mọ ipari kọrọ na. O si bọ si ọkankan gan ile Alao Ojo, *Ford Car* yẹpẹrẹ kan ni. Mi o le sọ bi ọna na ti gboro to, ṣugbọn eyiti o ku ni ọna na to enia gba kọja. Mo ri Ojo ni ẹnu ọna ile rẹ. Oto ọpọlọpọ lo mọ ọti mu de gongo ti ọkan wọn si gba, wipe bi wọn mu tan o ni gborun rẹ lara wọn ... ko to mu tan orun ... ti gbọji kan "*Ọjọ ni awọn kolẹpa mi o-omi.*"

*Re Examination.* Dokita Vaughan *Motor* Alao Ojo yi wa ni ọwọ osi ọna ti Ọgbẹni Arthur Davies ni lati gba bẹni.

*Court. I adjourn this case till tomorrow 9 a.m. 26th.*

Nigbati Dokita Vaughan bu ọrọ sọ. Agogo kan nla lu, Adajọ ni on fi ẹjọ yi si ọla ni agogo mẹsan ijọ kẹrindilọgbọn oṣu *June, 1925*.

*[Koi ti pari.* ATOLUGBOKUN.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**CATHOLIC.**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)

MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

**ANGLICAN**

Time. Preacher.
9 a.m. Christ Church, Rev. F. W. Ainley
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) The Archdeacon
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. John's (Aroloya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Peter's (Alapako)
Bro. J. Majek Akinloye
6.30 p.m. " C. Kasumu
9 a.m. Holy Trinity (Ebute-Ero)
6.30 p.m.
9 a.m. St. David's (Jordan) Rev. J. H. Ogunro
6.30 p.m. do.

**WESLEYAN**

10.30 a.m. Tinubu Rev. D. A. Bababnumi
7 p.m. do. Rev. D. A. Tekoe
10.30 a.m. Ereko Rev. L. R. Potts-Johnson
7 p.m. do. Rev. D. A. Bababunmi
10.30 a.m. Olowogbowo Rev. S. A. Pearce
7 p.m. do. Rev. E. E. Williams
10.30 a.m. Ọbun Eko Bro. Samuel O. Taiwo
7 p.m. do Rev. S. A. Pearce
Williams' Memorial Wesleyan (Ebute Mẹta)
10.30 a. .m. Rev. A. N. Cole
7 p.m. Bro. A. T. Coker

**AFRICAN**

9 a.m. Jehovah Shalom Rev. Supd. D. A. Hughes
6.30 p.m. do. Bro. A. W. Williams
9 a.m. Christ Church (Ebute Meta)
6 p.m. do.
9 a.m. Bethel Rev J. Ṣotayọ Williams
6.30 p.m do. Rev. A. Abọyade-Cole
9 a.m. Zion Rev. N. J. D. Ṣomuji
6.30 p.m. do. do.
9 a.m Salem Church (Ebute Mẹta
Rev. N. T. Williams
6.30 p.m. do. Rev. J. A. Wright
9 a.m. Bethlehem Church (Ebute Mẹta)
Bro. M. T. Akinṣọwọn
4 p.m. Bro. J. E. Ṣowonọla

10. a.m. African Methodist Bro. W. K. Fafunwa
7 p.m. do. Bro. J. A. Oshodi

**BAPTIST**

10.30 a.m.
6.30 p.m. Rev. J. R. Williams
9 a.m. Ebenezer Bro. Jariọgbe Tubi
6.30 p.m. Rev. E. C. Alabi
9 a.m. Ararọmi Bro J. F. Oshodi
6 p.m. Rev. A. A. Puddicombe

**ISHOLARIAN.**

7.30 a.m. Ilupesi The Founder
7 p.m. do.

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Patriarch J. G. Campbell

**AHMADIA**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose
(Central Mosque, Arọloya Street.)

**ZION CONGREGATIONAL**

9 a.m. Kakawa St. Locum Tenens
7 p.m. do. do.

**ARMY**

10 a.m. Glover Memorial Hall
Capt. Jones and the cadets.
7 p.m. do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square
J. P. A. Taylor

**UNITARIAN**

10 a.m. The Minister. (Arapa Hall)
6.30 p.m. do. 21, Williams Street

**AFRICAN FAITHIST KOSMON**

5 p.m. 8, Shitta Street. Bro. A. Gbogboade

## IGBẸ L'OWO WÀ.

### EKO.

Bi ọ̀wọ̀ Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti kuṣi ọsẹ yi leyi :—

EKURỌ

£14 15—£15 fun *ton* kan

EPO.

£24 15 fun *ton* kan

COCOA.

£26—£28 fun *ton* kan

### KANO.

GROUND NUT.

£15 fun *ton* kan

"O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ọ kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo:—Otutu orịṣirịṣi, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara."




A HEALING CREAM

**Mentholatum**

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments.

**THE MENTHOLATUM COMPANY LTD., SLOUGH, ENGLAND.**

*Over 16 million jars sold last year.*

## *Electric Novelties.*

MARVELLOUS BARGAINS.

Mr. M. Sadiku has assorted kinds of Electric Materials, 2 & 3 lights, Brackets, Shades, etc., too numerous to mention.

And also undertakes the contract of wiring houses at very reasonable prices.

He has also in stock louder bells complete with wire and Salamonical ready for connections. Please call at 18 Ọbun Eko Street, Lagos and make your selection.

*P.O. Box 378.*

The West African Soap Co. Limited

APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

**NEPTUNE**

PALE SOAP

**BUGLE**

PALE SOAP

**MAGNET**

CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

F 393

## White's Golden Male Tonic

*(NATIVE)*

(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a woman has not been in the famil way for a long time, the fault is usually set dow to some disease or other in her generative organ

Now while it is true that many women suffe from disease yet many times the fault lies wit the man, owing to weakness or some other diseas of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated t give full vigour to the man, and to remove al diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, t cure or prevent weakness of the generative organ

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*

Packing & Postage 2/6. extra.

**SHAKE THE BOTTLE.**

AREMỌ FUN ỌKỌNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ęda ati gbogbo Arun ti ki ję ki ọkunrin şe abiamọ.

N.B.—O yę ki gbogbo ọkọnrin ma lo igo mejimeji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price ten shillings ( 10/- per bottle ).

## Saccharine! Saccharine!! Saccharine!!!

*Purer than Sugar, Sweeter than Sugar, Cheaper than Sugar and more economical than Sugar.*

Try it in your Cup of Tea Coaca, Coffee or in your Oats or Paps, you run no risk.

Saccharine is absolutely harmless even to the most delicate system; it is very good for young and old, it is now in use in many homes. "A boon to those who do not take Sugar and to travellers." If you are in doubt consult your physician.

1 Bottle of 600 Tablets for 1/3d.
1 ,, ,, 500 ,, ,, 1/-

*Good Bargains.*

Apply to the Manager :—

APALARA STORE,
72, Great Bridge Street
Ęnu-owa.

P.O. Box 772,
Lagos, Nigeria.

## J. G. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja *Excelsior* " ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo " Gbabiọgẹdẹ " nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ ( Işika ) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, ( l'ebute Olowu ) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, ( l'Anikantamọ ) l'Eko.

O nta Iworo ( Golu ) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

---

### Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. Pereira's, Şẹtẹolu Compound, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

### Coffin ! Coffin !! Coffin !!!

With excellent workmanship and finish on sale at Paul I. Samuel's Workshop 5, Campbell Street, Lagos.

PAUL I. SAMUEL,
*Builder & Contractor.*
Residence and Office 72, Igboşere Road Lagos.

---

### Ask From Kaduna Stores.

Everything for Bicycles, Motors, and Gramophones. Newly arrived Gramophones and Zonophones, at cheapest prices as follows :—

£1. 10s. od., £1. 15s. od. to £2. 0. 0.

We also stock special Louder Gramophone needles ; these needles play four-records at one time.

Yoruba and English reccords of the latest amusing time.

For Particulars apply to the Manager.

S. A. CLAY
No. 79, Ọdunfa Street, or
1, Macaulay Street,
Lagos.

---

Cable Address :—
" Steinafrik " HAMBURG

### E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neuerwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

---

### KERE O!

Iya-afin Mrs. Beckley nşu Akara didun ( *Cake* ) ta nile rẹ, ni 53, Opopo nla, ŏ gbeyawo ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ ; o sami fun ọmọ ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ ; o tọrọ ọmọ ni o, re yan tirẹ nibẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo rẹ.

# A. Kessler.

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

**Highly Recommended:**

THE

## Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**33s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**



### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati orişirişi arun ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

A nta Egbogi yi ni Ṣabu Egbogi Ogbẹni V White, 41, Offin Road, Lagos.

### WO'BI ẸNIKEJI,

Oniruru Posi li o wa fun tita; lọdọ I. Samuel owo wọn bẹrẹ lati Pọun abọ titi de Pọun mejila şile mejila. ri wọn ra ni 40, Campbell Street, Ile-isin Ṣọşi Ẹbenezer; ati ni No. Igboşere Road, nitosi *King's College*.

### White's Convulsion-Killer

*(NATIVE)*

(FOR BOTH CHILDREN AND ADUL

**Sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

**The Reliable Dispensary,**

**41, Offin Road, Lagos.**

DIRECTIONS:—For adults one Tablespo every halfhour until the fit is gone. As a pr tive, one Tablespoonful every morning b food. For Children, one desertspoonful, in same manner.

*Packing & Postage 1/3d. extra.*

"SHAKE THE BOTTLE."

### EGBOGI AIPERI.

(Fun Ọmọde ati Agbalagba.)

Akajuwe:—Fun Agbalagba, Ṣibi ti a fi njẹ meji-meji ni ababọ Wakati, titi aiperi na yi oluwa rẹ silẹ. Fun ọmọde şibi kọkan bakan

Ki Aiperi ma ba şeni:—Fun Agbalagba, ki fi şibi meji-meji tẹlẹ inu loro. Fun ọmode kọkan. Ki a mi igo na daradara ki a to mu e gi na.

PRICE FIVE SHILLINGS (5S) PER BOTTLE.


When replying advertise please mention *Eko Akete*.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.